<table>
<tr><td rowspan="2">UNIVERSITY of MARYLAND MEDICAL SYSTEM<br><br>Ètò Owó tó ń Wọlé</td><td>OJÚ-ÌWÉ:<br>1 NÍNÚ 13</td><td>NỌ́MBÀ ÀGBÉKALẸ̀:<br>RCS - 01</td></tr>
<tr><td>DÉÈTÌ TÓ BẸ̀RẸ̀:<br>09/18/19</td><td>(ÀWỌN) DÉÈTÌ ÀTÚNYẸWÒ:<br>07/01/23</td></tr>
<tr><td colspan="3">ÀKÒRÍ: UMMS Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó</td></tr>
</table>

**ÀWỌN KÓKÓ Ọ̀RỌ̀**:
Ìrànwọ́ Owó, Ìpènijà Owó, Ìwé Àṣẹ Ìnílò, Ìrànwọ́ Ìlera

**ÀFOJÚSÙN/ÌPÌLẸ̀:**
Èrèdí gbólóhùn àgbékalẹ̀ yìí ni láti ṣe àpèjúwe ìgbésẹ̀ ìbéèrè fún ìrànwọ́ owó, bí a ṣe ma ń ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìbéèrè fún ìrànwọ́ àti bí a ṣe ma ń pinnu lórí ẹni tó bá pegedé, àwọn àmúyẹ ìpegedé fún àwọn ètò ìrànwọ́ owó (tó fi mọ́ ìpegedé tí a f'ojúsùn àti ìrànwọ́ ìpènijà owó),ẹ̀rí ìpegedé aláìsàn tó nílò ìrànwọ́, bí UMMS ṣe ma ń fi tó àwọn aláìsàn létí nípa ìrànwọ́ owó tó wà nílẹ̀, ìgbésẹ̀ ìbẹ̀bẹ̀, àti àwọn ìṣe gbígba owó tó kọjá bó ṣe yẹ.

**BÍ A ṢE LÈ LÒÓ:**
Àgbékalẹ̀ yìí kan gbogbo àwọn ọmọ ikọ̀, àwọn alágbàtà, àti àwọn aṣojú [àwọn tí wọ́n fi ara wọn jìn, àwọn ọmọ ikọ̀ elétò ìlera] ní èyíkéyìí àwọn àjọ ọmọ ẹgbẹ́ University of Maryland Medical System:

- Ìbùdó Ìlera University of Maryland (UMMC)
- Ọgbà Ilé-ẹ̀kọ́ UM Midtown (MTC)
- Ilé-ẹ̀kọ́ UM Rehabilitation & Orthopaedic (UMROI)
- Ibùdó Ìlera UM St. Joseph (UMSJMC)
- Ibùdó Ìlera UM Baltimore Washington (UMBWMC)
- Etò Ìlera Ẹkùn UM Shore (UMSRH)
- Ibùdó Ìlera UM Shore ní Dorchester (UMSMCD)
- Ibùdó Ìlera UM Shore ní Easton (UMSME)
- Ibùdó Ìlera Ẹkùn UM Charles (UMCRMC)
- Ibùdó Ìlera UM Upper Chesapeake (UCHS)
- Ibùdó Ìlera Ẹkùn UM Capital (UMCRH)
- Àwọn Àkójọ àwọn Dókítà UM (UMPN)
- Ibùdó UMMS Outpatient Rx Weinberg
- Ibùdó Ìtajà Ògùn UMMC ní Redwood
- Ibùdó Ìtajà Ògùn UMMS
- Ibùdó Ìtajà Ògùn Ọgbà UMMC Mid-Town
- Ibùdó Ìtajà Ògùn UMMC ní Capital Region
- Ibùdó Ìtajà Ògùn UMMC ní Baltimore Washington

**ÀWỌN ÌTUMỌ̀:**

| | |
|---|---|
| Ìpele Ìṣẹ̀ òhun Òṣì Àpapọ̀ | Ìgbéléwọ̀n owó tó ń wọlé lọ́dọọdún ti Ẹ̀ka Ìlera àti Iṣẹ́ Ọmọnìyàn (HHS). Àwọn ìpele ìṣẹ̀ òhun òṣì àpapọ̀ ni a fi ń mọ ti ènìyàn bá pegedé fún àwọn ètò àti ànfààní kan. |
| Ìpènijà Owó | Àpẹẹrẹ níbití owó àjọ tó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ jẹ ní àwọn àjọ tó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ UMMS fún ìtọ́jú ìlera tó yẹ ti ẹbí kan láàrin oṣù méjìlá (12) tó kọjá ìdá 25% owó tó ń wọlé fún ẹbí náà lọ́dún. |
| Àwọn Ìwọ̀n MDH | Jẹ́ ìwọ̀n ìpegedé owó tó ń wọlé fún ìtọ́jú tí kò wọ́n lówó, èyí tí Ẹ̀ka Ìlera Maryland (MDH) ti ilé-iṣẹ́ tó ń rí sí Ètò Ìrànwọ́ Ìlera ṣètò. Ìpínlẹ̀ Maryland fọwọ́sí ìmógbòrò ètò Ìrànwọ́ Ìlera Àpapọ̀ Federal Medicaid ní 1 oṣù kínní, ọdún 2014 àti Ìpele Ìṣẹ́ òhun Òṣì Àpapọ̀, lábẹ́ òfin Ìtọ́jú tí kò Gunpá ìyẹn Affordable Care Act, èyí tó ṣe ìmógbòrò òpin owó tó ń wọlé tó pegedé fún ètò Medicaid ní Maryland. UMMS fọwọ́sí àwọn òpin tuntun wọ̀nyí fún àdínkù ìwọ̀n owó ìtọ́jú, bó ti ṣe wà ní àsopọ̀ A. |
| Gbèsè Ètò Ìlera | Àwọn owó tí a san láti àpò ara wa, tó fi mọ́ àwọn owó-àjọsan, àwọn owó tó yẹ láti yọ, tí ènìyàn jẹ láwọn àjọ ọmọ ẹgbẹ́ UMMS fún ìtọ́jú ìlera tó yẹ. |
| Ìpegedé tí a F'ojúsùn | Tó bá ṣẹlẹ̀ pé àlàyé tí aláìsàn fi sílẹ̀ tàbí nípasẹ̀ àwọn orísun mìíràn pèsè ẹ̀rí tó tó pé aláìsàn náà pegedé fún ìrànwọ́ owó, ṣùgbọ́n tí kò sí fọ́ọ̀mù ìrànwọ́ nínú fáìlì. |

## ÀGBÉKALẸ̀:

Ètò Ìlera ní Fásitì Maryland ìyẹn University of Maryland Medical System ("UMMS") farajìn sí pípèsè ìrànwọ́ fún àwọn ènìyàn tí wọ́n ní ìnílò ìlera tí wọn kò sì ní ìdíyelófò, tí ìdíyelófò wọn kò tó, kò yẹ fún ètò ìjọba, tàbí tí kò rí owó san, fún ìtọ́jú ìlera pàjáwìrì tó yẹ èyí tó dá lórí bí ẹnìkọ̀ọ̀kan ṣe nílò owó sí.

Àgbékalẹ̀ àwọn àjọ ọmọ ẹgbẹ́ University of Maryland Medical System ("UMMS") láti pèsè ìrànwọ́ owó èyí tó ṣe déédé tàbí tayọ àwọn ìbéèrè Ìpínlẹ̀ Maryland fún àwọn aláìsàn tó bá àwọn àlàkálẹ̀ àmúyẹ owó pé tó sì bèrè fún ìrànwọ́ bẹ́ẹ̀.

I. **Ìtọ́jú Ọ̀fẹ́ -** Àwọn tí owó tó ń wọlé fún wọn tó ìdá 200% òpin ìpegedé owó tó ń wọlé èyí tí Ẹ̀ka Ìlera Maryland ṣèdásílẹ̀ pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́.
II. **Ìtọ́jú Ẹ̀dínwó -** Àwọn tó wà láàrin ìdá 200% àti 300% òpin ìpegedé owó tó ń wọlé èyí tí Ẹ̀ka Ìlera Maryland ṣèdásílẹ̀ yẹ fún ẹ̀dínwó, bó ti ṣe wà ní àsopọ̀ A.
III. **Ìpènijà Owó -** Àwọn tí wọn kò pegedé fún ìrànwọ́ owó lábẹ́ àwọn ìtọ́sọ́nà àgbékalẹ̀ yìí, ṣùgbọ́n fún àwọn tí gbèsè ìtọ́jú tí wọ́n jẹ ní gbogbo àwọn ibùdó tó jẹ́ alábàṣepọ̀ UMMS kọjá ìdá 25% Owó tó ń Wọlé fún Ẹbí, yẹ fún ìrànwọ́ ìpènijà owó.

Àwọn ètò owó sísan náà wà fún gbogbo aláìsàn. Àwọn ètò lè jẹ́ títúnṣe tí aláìsàn bá bèrè. Àlékún àlàyé lórí àwọn ètò owó sísan wà nínú Àgbékalẹ̀ Ètò Owó Sísan UMMS. UMMS nìkan ṣì ló ní ẹ̀tọ́ láti pinnu ìkápá aláìsàn láti sanwó. Gbogbo àwọn aláìsàn tí wọ́n gbé wá fún àwọn iṣẹ́ pàjáwìrì ni a yóò tọ́jú láì fi ti ìkápá wọn láti sanwó ṣe. Fún àwọn iṣẹ́ pàjáwìrì/kíákíá, ìbèrè fún ìrànwọ́ owó yó jẹ́ píparí, a yó gbàá, tí a yó sì ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ tí kò sì ní fa ìdádúró fún aláìsàn láti gba ìtọ́jú.

## ÌLÀNÀ:

### I. Bí Ènìyàn Ṣe Le Bèrè Fún Ìrànwọ́ Owó

Fún èyíkéyìí ìtọ́jú, ìgbésẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó yó ṣí sílẹ̀ fún ó kéré jù ọjọ́ 240 lẹ́yín tí wọ́n fi iye àkọ́kọ́ tí owó ìtọ́jú aláìsàn jẹ́ ránṣẹ́ lẹ́yìn tí wọ́n ti ní kó máa lọ ilé. Àwọn aláìsàn lè bèrè fún ìrànwọ́ owó ṣaájú tàbí lẹ́yìn tí wọ́n gba ìtọ́jú, tàbí a lè toka wọn gẹ́gẹ́ bíi ẹni tó ṣeéṣe kó gba ìrànwọ́ owó lásìkò ìgbésẹ̀ ìfúnni ní ìwé àṣẹ ìnílò owó tàbí àyẹ̀wò ìpegedé fún ìrànwọ́ owó tí a f'ojúsùn.

Ìwé àṣẹ ìnílò owó jẹ́ ìgbésẹ̀ tó ma ń pinnu ìkápá tàbí tó bá ṣe ṣeéṣe sí fún aláìsàn láti sanwó. Nígbà tó bá ṣeéṣe a yó tiraka láti pèsè ìwé àṣẹ ìnílò owó ṣaájú ọjọ́ ìtọ́jú. Lásìkò ìgbésẹ̀ ìfúnni ní ìwé-àṣẹ ìrànwọ́, àwọn aláìsàn tí wọ́n ní àwọn kò ní iṣẹ́ tí wọn kò sì ní ìdíyelófò ni a yó ní kí wọ́n fi ìbèrè fún ìrànwọ́ owó ṣọwọ́ kí wọ́n tó gba ìtọ́jú ìlera tí kìí ṣe pàjáwìrì (àfi tí wọ́n bá pé gbogbo àwọn àmúyẹ ìpegedé fún ìrànwọ́ owó tí a f'ojúsùn).

Ìgbésẹ̀ ìbèrè ẹyọ̀kan ni yó wà fún gbogbo àwọn ibùdó ìlera tó jẹ́ alábàṣepọ̀ UMMS. UMMS yó tẹ́wọ́gba ìbèrè fún ìrànwọ́ owó (àti àwọn ìnílò tó yẹ) ti àwọn Onísègùn Aṣètọ́jú, Inc.'s (FPI) láti pinnu ìpegedé fún ètò Ìrànwọ́ Owó UMMS. Àwọn aláìsàn nílò láti pèsè ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó (pẹ̀lú gbogbo àlàyé àti àkọsílẹ̀ tó yẹ), àyàfi tí wọ́n bá ní àwọn àmúyẹ fún ìpegedé tí ó f'ojúsùn. Láti gbé ìgbésẹ̀ yìí, ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn aláìsàn gbọdọ̀ pèsè àlàyé nípa ìwọ̀n ẹbí àti owó tó ń wọlé. A yó tẹ́wọ́gba fífi ẹnu fi àwọn àlàyé tó nílò sílẹ̀, níbi tó bá yẹ. UMMS yó pèsè ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó fún gbogbo àwọn aláìsàn ní ipòkípò yòówù kí ìdíyelófò ìlera wọn wà, tó fi mọ́ àwọn aláìsàn tí wọn kò ní ìdíyelófò, tí ìforúkọsílẹ̀ náà yó sì wà ní ojú-òpó wẹ́ẹ̀bù UMMS àti tí aláìsàn bá bèrè.

<u>**Ṣíṣe Àtìlẹ́yìn Àkọsílẹ̀ fún àwọn Ìbèrè fún Ìrànwọ́ Owó**</u>

Láti bá àwọn olùforúkọsílẹ̀ parí ìgbésẹ̀ náà, a yó gbé gbogbo àkọsílẹ̀ tó yẹ àti tí a dába sórí ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó, tó fi mọ́:

- Ẹ̀dà Ìwé Owó Orí tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ san (tí o bá ti ṣe ìgbéyàwó tí ẹ sì ń sanwó ní ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀, fi ẹ̀dà ìwé owó orí ẹnìkejì náà síi); ẹ̀rí owó tó ń wọlé fún àkàndá (tó bá nííṣe), ẹ̀rí owó ààbò àwùjọ (tó bá nííṣe).
- Tí wọn kò bá ní iṣẹ́ lọ́wọ́, ẹ̀rí àìníṣẹ́ bíi àtẹ̀jáde láti Ilé Iṣẹ́ tó ń rísí Ìdíyelófò Àìníṣẹ́, àtẹ̀jáde láti orísun àtìlẹ́yìn owó lọ́wọ́lọ́wọ́, àti bẹ́ẹ̀bẹ́ẹ̀ lọ.
- Ẹ̀dà ìwé owó tí wọ́n ṣẹ̀ṣẹ̀ gbà (tí wọ́n bá n'íṣẹ́ lọ́wọ́) tàbí ẹ̀rí owó tó ń wọlé mìíràn.
- Ìfitónilétí Ìpinnu fún Ìrànwọ́ Ìlera (tó bá yẹ).
- Ẹ̀dà Ìwé Owó Ilé (tó bá nííṣe), tàbí àkọsílẹ̀ ipò ìgbé wọn lọ́wọ́lọ́wọ́.
- Tí aláìsàn bá fi ẹ̀dà Ìwé Owó Orí Sísan àti ìwé owó tó ń wọlé fún wọn sílẹ̀ (tàbí ẹ̀rí owó tó ń wọlé mìíràn), tí ọ̀kan nínú àwọn àkọsílẹ̀ méjèèjì nìkan ló fi hàn pé wọ́n pegedé fún ìrànwọ́ owó, àkọsílẹ̀ tó tuntun jù ni yó sọ ìpegedé.

A lè má kọ ìrànwọ́ owó látàrí ìyọkúrò àlàyé tàbí àkọsílẹ̀ tí kò nílò ní pàtó fún àgbékalẹ̀ yìí tàbí lórí ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó, UMMS sì ní ẹ̀tọ́ láti ṣe ìrànwọ́ owó fún àwọn aláìsàn tí kò tíì pèsè gbogbo àkọsílẹ̀ tó yẹ.

- Tí aláìsàn bá fi ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó ṣọwọ́ láì sí àlàyé àti àkọsílẹ̀ tó yẹ fún ìpinnu ìkẹhìn ìpegedé, a yó fi ìbéèrè fún àlàyé àti àkọsílẹ̀ náà fi ránṣẹ́ sí aláìsàn náà.
- Ìbéèrè náà yó ní àlàyé bí a ṣe lè kàn sí (tó fi mọ́ nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àti àdírẹ́sì ilé-iṣẹ́) ilé-iṣẹ́ tàbí ẹ̀ka tó lè pèsè àlàyé nípa ìrànwọ́ owó àti ìrànwọ́ lórí ìgbésẹ̀ ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè.
- Aláìsàn náà yó ní ọgbọ̀n (30) ọjọ́ bẹ̀rẹ̀ láti ìgbà tí a pèsè ìbéèrè yìí láti fi àlàyé àti àkọsílẹ̀ tó yẹ sílẹ̀ kó lè baà pegedé. Tí a kò bá gba àlàyé náà láàrin ọjọ́ 30 náà, a yó fi àtẹ̀jíṣẹ́ ránṣẹ́ láti fi tó aláìsàn létí pé ọ̀rọ̀ náà ti parí nítorí àìsí àkọsílẹ̀ tó yẹ.
- Aláìsàn náà lè tún padà forúkọsílẹ̀ fi bèrè ìrànwọ́ owó kó sì bẹ̀rẹ̀ ọ̀rọ̀ tuntun nípasẹ̀ fífi àlàyé àti àkọsílẹ̀ tí kò sí níbẹ̀ sílẹ̀.

**II. Ṣíṣe Àgbéyẹ̀wò àti Ìpinnu Ìpegedé àwọn Ìforúkọsílẹ̀ Ìbèrè fún Ìrànwọ́ Owó**

Àwọn ọmọ ikọ̀ tí a yàn wà tí wọn yó máa gba àwọn ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó. Àwọn ọmọ ikọ̀ náà lè jẹ́ àwọn agbanilámọ̀ràn lórí ìnáwó, àwọn adarí lọ́rọ̀ owó tó jẹ́ ti aláìsàn, àwọn aṣojú létò onígbàára tàbí àwọn àjọ mìíràn tí wọ́n ń ṣiṣẹ́ gẹ́gẹ́ bíi ẹ̀ka ilé-iṣẹ́ ìdókoòwò ààrin gbùngbùn. Láti bá olùforúkọsílẹ̀ parí ìgbésẹ̀ náà, UMMS yó pèsè ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó tí yó jẹ́ kí wọ́n mọ irú ìwé wo ló yẹ fún ìpinnu ìkẹhìn fún ìpegedé. Níbi tó bá ṣeéṣe, àwọn ọmọ ikọ̀ yó kàn sí ọ lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ tàbí pàdé àwọn aláìsàn tí wọ́n bèrè fún ìrànwọ́ owó láti pinnu tí wọ́n bá ní àwọn àmúyẹ fún ìrànwọ́.

A yó fi àwọn àlàyé ìbẹ̀rẹ̀ sí orí ẹ̀rọ mìíràn léyí tí yó jẹ́ kí àwọn ọmọ ikọ̀ tí a yàn láti mójútó ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè náà kí wọ́n sì pinnu ìpegedé fún ìrànwọ́ owó. Àwọn ọmọ ikọ̀ tí a yàn yó:

- Pinnu bóyá aláìsàn ní ìdíyelófò ìlera tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́. Àwọn aláìsàn tí wọ́n ní anfààní sí ètò ìlera mìíràn (fún àpẹẹrẹ ètò ìdíyelófò àkọ́bẹ̀rẹ̀ tàbí ìkejì, tàbí àwọn elétò tó yẹ), gbọdọ̀ ṣàmúlò gbogbo ànfààní wọn tán kí wọ́n tó bèrè fún ìrànwọ́ owó.
- Tí aláìsàn náà bá yẹ fún ètò COBRA, ọmọ ikọ̀ tí a yàn yó ṣe àgbéyẹ̀wò ìkápá aláìsàn láti san ìdíyelófò COBRA tí yó sì dábàá fún àwọn Adarí Àgbà.

- Parí àyẹ̀wò ìpegedé pẹ̀lú ètò Medicaid fún àwọn aláìsàn tí wọ́n Sanwó Fúnra wọn láti ṣàrídájú bóyá aláìsàn náà ní ìdíyelófò lọ́wọ́lọ́wọ́. Láti gbé ìgbésẹ̀ yìí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn olùforúkọsílẹ̀ gbọdọ̀ pèsè àlàyé nípa ìwọ̀n ẹbí àti owó tó ń wọlé.
- Pinnu bóyá aláìsàn náà ṣeéṣe kó yẹ fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó.
- Pinnu bóyá àwọn aláìsàn tí wọ́n kò ní ìdíyelófò yẹ fún ìdíyelófò ìlera ti gbogbogbò tàbí ti àdáni. A yó gba ẹnìkọ̀kan tó bá ní ìkápá láti ṣe ìdíyelófò ìlera níyànjú láti ṣe bẹ́ẹ̀, gẹ́gẹ́ bíi ọ̀nà láti ṣe àrídájú ètò ìlera àti fún ànfààní ìlera ara wọn.

Dé ibi tó bá ṣeéṣe dé, àwọn ọmọ ikọ̀ tí a yàn yó pèsè ìrànwọ́ fún àwọn aláìsàn tí kò ní ìdíyelófò tí aláìsàn náà bá forúkọsílẹ̀ fún ìdíyelófò gbogbogbò tàbí ti àdáni, wọn yó pinnu bóyá aláìsàn náà pegedé fún àwọn ètò gbogbogbò mìíràn tó lè ṣe ìrànwọ́ pẹ̀lú owó ìtọ́jú ìlera, tí wọn yó sì lo àlàyé tó wà ní àrọ́wọ́tó UMMS láti pinnu bóyá aláìsàn náà pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó lábẹ́ àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó UMMS.

Láàrin ọjọ́ iṣẹ́ méjì tí a bá gba ìbéèrè aláìsàn fún ìrànwọ́ owó tàbí ìbéèrè fún ìrànwọ́ ìtọ́jú ìlera, UMMS gbọ́dọ̀ ṣe ìpinnu ìpegedé tó ṣeéṣe. Ìpinnu ìpegedé tó ṣeéṣe lè yí padà, èyí dá lórí tí àwọn àkọsílẹ̀ tó yẹ bá jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà.

Tí wọ́n bá pinnu pé ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó àlàìsàn ti parí tó sì yẹ, ọmọ ikọ̀ tí a yàn yó dábàá bí aláìsàn náà ṣe pegedé sí tí yó sì fi ṣọwọ́ fún ìfọwọ́sí ìkejì àti ìparí. UMMS yó pèsè ìpinnu ìkẹhìn lórí ìpegedé aláìsàn láàrin ọjọ́ 14 lẹ́yìn tí aláìsàn náà bá fi ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó tó parí ṣọwọ́ tó sì mú ìdádúró bá owó jíjẹ lásìkò ìgbà tí wọ́n ń pinnu bóyá ó pegedé.

**<u>Tí a bá Fọwọ́sí Ìbéèrè fún Ìrànwọ́ Owó</u>**
Ní kété tí a bá fọwọ́sí aláìsàn fún ìrànwọ́ owó, ètò ìrànwọ́ owó bẹ̀rẹ̀ fún oṣù ìpinnu àti ọdún kan ṣaájú ìpinnu náà.

- A yó fi lẹ́tà ìpinnu ìkẹhìn ṣọwọ́ sí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn aláìsàn tí wọ́n ti bèrè fún ìrànwọ́ owó, tó fi mọ́ (tó bá níìṣe): ìrànwọ́ tí ènìyàn pegedé fún àti ìdí ìpinnu náà.
- UMMS lè pinnu láti sún gbèdéke ìpegedé fún ìrànwọ́ owó sẹ́yìn tàbí síwájú lábẹ́ bó ṣe wù kó rí.
- Ìrànwọ́ owó wà fún gbogbo ìtọ́jú pàjáwìrì àti àwọn ìtọ́jú ìlera mìíràn tí àwọn alábáṣepọ̀ UMMS pèsè (wo àwọn Ìyàsọ́tọ̀ fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé).
- Tí wọ́n bá pèsè àlékún ètò ìtọ́jú ìlera tayọ àkókò ìpegedé, àwọn aláìsàn gbọdọ̀ tún ìrànwọ́ owó bèrè.
- Tí a bá pinnu pé aláìsàn náà yẹ fún ìtọ́jú ẹ̀dínwó, tó sì ti gba ìwé fún ètò ìtọ́jú ìlera tó gbà lásìkò ètò ìrànwọ́ owó, a yó fún aláìsàn náà ní àtẹ̀jáde àkọsílẹ̀ owó tó ń ṣàfihàn iye owó ìtọ́jú tí aláìsàn náà jẹ lẹ́yìn tó gba ìrànwọ́ owó.
- Tí aláìsàn kan bá sanwó ìtọ́jú ṣaájú kó tó rí ìrànwọ́ owó gbà, a lè dá owó padà fún wọn. Ìpinnu dídá owó padà dá lórí ìgbà tí a pinnu pé aláìsàn náà ò rí owó san ní àfiwé ìgbà tí wọ́n sanwó aláìsàn. Tí iye owó tí a pinnu pé aláìsàn ríbi san kéré sí iye owó tí aláìsàn san, a yó dá owó tó kù padà fún aláìsàn tí iye owó náà bá fi $5.00 tàbí jù bẹ́ẹ̀ lọ ju iye owó tí a pinnu kí aláìsàn san lọ. Èyí pẹ̀lú àwọn ìpinnu ìpegedé fún ìrànwọ́ owó láàrin ọjọ́ 240 lẹ́yìn tí a pèsè ìwé owó àkọ́kọ́.

Tí àyípadà bá wà nínú owó tó ń wọlé fún aláìsàn, àwọn dúkìá, owó níná tàbí ipò ẹbí, ó yẹ kí aláìsàn náà ó fi tó Ẹ̀ka Ìrànwọ́ Owó létí ní 410-821-4140. Láti gbé ìgbésẹ̀ yìí, àti láti rìi dájú pé àwọn aláìsàn ní anfààní láti jẹ́ àtúnyẹ̀wò fún ìpegedé fún ìrànwọ́ owó láàrin ọjọ́ 240 ti àtẹ̀jáde àkọsílẹ̀ àkọ́kọ́,UMMS yó fi tó àwọn aláìsàn létí pé tí owó tó ń wọlé fún wọn bá ti yípadà, kí wọ́n kàn sí Ẹ̀ka Ètò Ìrànwọ́ Owó lórí àtẹ̀jáde àkọsílẹ̀ kọ̀ọ̀kan.

**Tí a kò bá Fọwọ́sí Ìbéèrè fún Ìrànwọ́ Owó**

Tí a bá pinnu pé aláìsàn kan kò pegedé fún ìrànwọ́ owó ṣaájú kí ó tó gba ìtọ́jú (fún ìtọ́jú náà), gbogbo ìlàkàkà láti gba owó tí o san, àwọn owó tí a yọ, tàbí ìdá kan nínú owó ìtọ́jú náà tí ìrètí wà pé yó ṣẹ́kù fún ìtọ́jú náà ni a yó pèsè ṣaájú ọjọ́ ìtọ́jú tàbí lọ́jọ́ ìtọ́jú.

- Tí a bá pinnu pé aláìsàn náà kò pegedé fún ìrànwọ́ owó, tí wọ́n sì forúkọsílẹ̀ lójúnà àti gba ẹ̀rí ìpegedé fún ìtọ́jú tí kìí ṣe pàjáwìrì, ọmọ ikọ̀ tí a yàn yó fi tó àwọn òṣìṣẹ́ elétò ìlera létí nípa ìpinnu náà tí a kò sì ní fi ayé sílẹ̀ fún ìtọ́jú tí kìí ṣe pàjáwìrì náà.
- Òṣìṣẹ́ elétò ìlera lè bẹ̀bẹ̀ lórí ìpinnu yìí kó sì bèrè fún àtúnwòṣe Ìgbìmọ̀ tó wà fún ọ̀rọ̀ Ẹ̀rí Ìpegedé Ìrànwọ́ Owó.
- Fún ìtọ́jú pàjáwìrì tàbí kíákíá, ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó yó jẹ́ píparí, gbígbà àti gbígbéyẹ̀wò tí kò sì ní dá àwọn aláìsàn dúró láti gba ìtọ́jú.
- Àwọn aláìsàn tí wọn kò pegedé fún ìrànwọ́ owó ni yó nílò kí wọ́n san èyíkéyìí àwọn àjẹsílẹ̀ owó wọn tí ó sì le jẹ́ kíkọ gẹ́gẹ́ bíi gbèsè tó burú tí owó náà kò bá jẹ́ sísan lásìkò tí a fẹnukò sí.
- Aláìsàn náà lè bẹ̀bẹ̀ lórí ìpinnu náà, jọ̀wọ́ wo abala Ẹ̀bẹ̀ Kòtẹ́milọ́rùn fún ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé.
- Fún èyíkéyìí ìtọ́jú, ìgbésẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó yó ṣí sílẹ̀ fún ó kéré jù ọjọ́ 240 lẹ́yín tí wọ́n fi iye àkọ́kọ́ tí owó ìtọ́jú aláìsàn jẹ́ ránṣẹ́ lẹ́yìn tí wọ́n ti ní kó máa lọ ilé.

**III. Àwọn Àmúyẹ Ìpegedé**

UMMS yó pèsè ìrànwọ́ owó tí wọ́n bá ti ṣe àgbéyẹ̀wò ipò ìnáwó aláìsàn tó sì ti wà ní àkọsílẹ̀. UMMS kò ní lo ipò ìjẹ́ ọmọ ìlú tàbí ìwọ̀lú gẹ́gẹ́ bíi àmúyẹ ìpegedé fún ìrànwọ́ owó; tàbí kọ̀ láti pèsè ìrànwọ́ owó fún aláìsàn nítorí ẹ̀yà, àwọ̀, ẹ̀sìn, orílẹ̀-èdè, ìran, akọ tàbí abo, ọjọ́-orí, bóyá èniyàn ti ṣe ìgbéyàwó tàbí bẹ́ẹ̀ kọ́, tàbí bóyá èniyàn jẹ́ àkàndá.

Àwọn àmúyẹ wọ̀nyí ni a yó lò láti fi mọ̀ bóyá aláìsàn pegedé fún ìrànwọ́ owó, ìrànwọ́ owó tí a f'ojúsùn, àti ìpegedé fún ìrànwọ́ ìpènijà owó.

**Ìpegedé fún Ìrànwọ́ Owó**

UMMS yó wo ìwọ̀n owó tó ń wọlé fún ilé ti MDH láti pinnu ìpegedé fún ìrànwọ́ owó àti ìpele ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó láti fún àwọn aláìsàn tó bá yẹ ní ìrànwọ́ owó. UMMS yó ṣe ìṣirò iye owó tó ń wọlé fún ẹbí (ilé) aláìsàn lásìkò ìtọ́jú. Láti lè mọ tí àyípadà kankan bá wà nínú bí owó ṣe ń wọlé fún ẹbí aláìsàn sí, UMMS yó tún iye owó tó ń wọlé fún ẹbí (ilé) ṣí láàrin ọjọ́ 240 tí a pèsè ìwé owó ìwòsàn àkọ́kọ́.

UMMS lè wo àwọn ohun ìní ilé tó jẹ́ ti owó láti pinnu lórí ìpegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó lábẹ́ àgbékalẹ̀ ìrànwọ́ owó ní àfikún àwọn àmúyẹ tó dá lórí owó tó ń wọlé. Àwọn ohun ìní tó jẹ́ ti owó ní a yó ṣàtúnṣe lọ́dọọdún fún àlékún ní ìbámu pẹ̀lú Ìwọ̀n Ìdíyelé Oníbàárà. À yó dá àwọn ohun ìní tó ṣeé sọ di owó wọ̀nyí sí:

- Ní ó kéré jù, $10,000 àkọ́kọ́ ohun ìní tó ṣeé sọ d'owó.
- Ilégbé tí iye rẹ̀ tó $150,000.
- Àwọn ohun ìní ìfẹ̀hìntì tí Àjọ Apawówọlé Lábẹ́nú ti gbé owó-orí lé gẹ́gẹ́ bíi akoto ìfẹ̀hìntì, tó fi mọ́ àwọn ètò àjẹmọ́nú tí a tọ́jú tó pegedé lábẹ́ Òfin Owó tó ń Wọlé Lábẹ́nú tàbí àwọn ètò àjẹmọ́nú tí a tọ́jú tí kò pegedé.
- Ọkọ̀ kan tí wọ́n ń lò fún aláìsàn tàbí èyíkéyìí mọ̀lẹ́bí aláìsàn;

- Èyíkéyìí ohun tí wọ́n yọ sílẹ̀ láti mọ ìpegedé fún ìrànwọ́ owó lábẹ́ Ètò Ìrànwọ́ Ìlera lábẹ́ Òfin Ààbò Àwùjọ.
- Owó ètò ẹ̀kọ́ gíga nínú akoto owó Ètò Maryland 529.

Láti mọ iye owó tó ń wọlé fún ẹbí aláìsàn, UMMS yó lo ìtúmọ̀ ìwọ̀n ilé tó jẹ́ wípé aláìsàn àti, ní ìwọ̀nba, ọkọ tàbí aya (láì wo bóyá aláìsàn àti ọkọ tàbí aya rẹ̀ lérò láti máa dìjọ san owó-orí ìjọba Ìpínlè tàbí ti ìjọba Àpapọ̀), àwọn ọmọ bíbí inú rẹ̀, àwọn ọmọ àgbàtọ́, tàbí ọbàkan, àti ẹnikẹ́ni tí aláìsàn náà kò fẹ́ kí owó-orí ìjọba àpapọ̀ tàbí ti Ìpínlẹ̀ kàn. Fún aláìsàn tó jẹ́ ọmọdé, ìwọ̀n ilé yó jẹ́ ọmọdé náà àti àwọn òbí tó bíi, àwọn òbí tó gbàà tọ́, àwọn ọmọ bíbí inú ìyá rẹ̀, àwọn ọmọ tí ìyá rẹ̀ gbà tọ́, àwọn ọmọ bàbá rẹ̀ àti ẹnikẹ́ni tí aláìsàn náà kò fẹ́ kí owó-orí ìjọba àpapọ̀ tàbí ti Ìpínlẹ̀ kàn.

A lè ní aláìsàn ò pegedé fún ìrànwọ́ owó:

- Tí wọ́n bá ní ètò ìdíyelófò (fún àpẹẹrẹ, HMO, PPO, tàbí Àjẹmọ́nú àwọn Òṣìṣẹ́, Medicaid, tàbí àwọn ètò ìdíyelófò mìíràn), tí kò f'àyè gba UMMS nítorí ìhámọ́/ìwọ̀n ètò ìdíyelófò.
- Tí wọ́n bá kọ̀ láti fa ara wọn sílẹ̀ fún àyẹ̀wò fún àwọn ètò ìrànwọ́ mìíràn ṣaájú kí wọ́n tó forúkọsílẹ̀ fún ìrànwọ́ owó.
- Tí wọ́n bá kọ̀ láti ṣe àlàyé lórí ẹjọ́ tí wọ́n ní nílé-ẹjọ́.

Ìrànwọ́ owó ma ń wà fún gbogbo pàjáwìrì àti àwọn ìtọ́jú ìlera mìíràn tí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn alábáṣepọ̀ UMMS pèsè; wàyí ò, àwọn ìyàsọ́tọ̀ yìí lè wáyé:

- Àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú láti ọwọ́ àwọn elétò ìlera tí wọn kò kí ń ṣe alábáṣepọ̀ UMMS (fún àpẹẹrẹ, àwọn ohun èlò ìtọ́jú ìlera, ìtọ́jú ìlera nínú ilé).
- Iṣẹ́ ìtọ́jú tí ètò tàbí àgbékalẹ̀ ìdíyelófò aláìsàn kọ̀ (fún àpẹẹrẹ, HMO, PPO, tàbí Àjẹmọ́nú àwọn Òṣìṣẹ́). A lè ṣe ìyàsọ́tọ̀ látàrí ọ̀rọ̀ kọ̀ọ̀kan tí a bá ní ká wo àwọn ohun tó lè fà nípa ti ìlera àti ètò.
- Ohun ìṣaralóge tàbí àwọn iṣẹ́ mìíràn tí kìí ṣe ti ìtọ́jú ìlera.
- Àwọn ohun amáyédẹrùn fún aláìsàn, oúnjẹ, àti ibùgbé.
- Ilégbé àti oúnjẹ tí a mójútó nígbà tí aláìsàn bá wà ní Ètò Ojúmọmọ.
- Ìdíyelófò Ìjànbá (Ìjànbá Ọkọ̀, Àjẹmọ́nú Òṣìṣẹ́, Ìfarapa tàbí àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn tó wà lábẹ́ ìdíyelófò)

Ìrànwọ́ owó fún owó ìtọ́jú akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí a bèrè lábẹ́ àgbékalẹ̀ yìí wà fún Àkójọ àwọn Dókítà UM (UMPN). Àwọn aláìsàn tí wọ́n fẹ́ wá ìrànwọ́ owó fún owó ìtọ́jú tí kìí ṣe ti Àkójọ àwọn Dókítà UM gbọdọ̀ kàn sí dókítà náà fúnra wọn. Àtòkọ àwọn tí wọn ń pèsè ìtọ́jú ní ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn ilé ìwòsàn UMMS ni ènìyàn lè rí ní àwọn ojú-òpó wẹ́ẹ̀bù àwọn ilé ìwòsàn UMMS kọ̀ọ̀kan. Àtòkọ yìí sọ ní pàtó èwo nínú àwọn tí wọ́n pèsè ìtọ́jú ìlera náà ni kò kópa nínú Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó UMMS.

**<u>Ìpegedé fún Ìrànwọ́ Owó tí a F'ojúsùn</u>**

Tó bá ṣẹlẹ̀ pé kò sí ẹ̀rí tó fìdí ẹ̀ múlẹ̀ pé aláìsàn pegedé fún ìrànwọ́ owó, UMMS lẹ́tọ́ láti pinnu lórí ìpegedé fún ìrànwọ́ owó àfojúsùn fún gbogbo akoto owó ilé ìwòsàn. Láti pinnu lórí ìpegedé àfojúsùn fún ìrànwọ́ owó, UMMS lè lo àwọn àjọ ní ìta tàbí àlàyé láti ṣe ìṣirò owó tó ń wọlé tí a lè lò láti wo bóyá aláìsàn pegedé fún ìrànwọ́ owó. Látàrí bí ọ̀rọ̀ àfojúsùn ṣe ma ń rí, UMMS yó pèsè ìtọ́jú ọ̀fẹ́ fún àwọn aláìsàn tí a bá f'ojúsùn pé wọn yó pegedé fún ìrànwọ́ owó. Ìpegedé àfojúsùn fún ìrànwọ́ owó yó wà lórí ọjọ́ tí aláìsàn gba ìtọ́jú nìkan. Àkójọ

àwọn Dókítà UM yó pèsè ìrànwọ́ owó lórí owó tó ṣẹ́kù tí dókítà yó gbà èyí tó dá lórí ìpinnu ìpegedé lórí owó tó ṣẹ́kù tí ilé ìwòsàn yó gbà.

A lè pinnu lórí ìpegedé àfojúsùn lórí bí ǹkan ṣe rí nínú ayé ẹnìkọ̀kan tó lè jẹ́:

a. Ètò Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera ògùn ọ̀fẹ́
b. Ètò Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera fún àwọn tí Owó tó ń Wọlé fún wọn Kéré (SLMB)
c. Ètò Ìtọ́jú àwọn Àgbà (PAC)
d. Àìnílélórí
e. Aláìsàn ní ètò Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera
f. Àwọn aláìsàn Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera àti Ìtọ́jú tí Àjọ Medicaid ń Ṣàkóso fún àwọn ìtọ́jú tí wọn ń pèsè ní ER tó kọjá àwọn ètò wọ̀nyí
g. Iye owó tí Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera ná sílẹ̀
h. Ìpegedé fún àwọn ètò ìrànwọ́ ìpínlè tàbí ìbílẹ̀ mìíràn, bíi:
   i) Ètò Àlékún Ìrànwọ́ Oúnjẹ
   ii) Ètò Ìrànwọ́ Agbára Ìpínlẹ̀
   iii) Àkànṣe Ètò Àlékún Oúnjẹ fún àwọn Obìnrin, àwọn ọmọ Ìkókó, àti àwọn Ọmọdé
   iv) Ètò iṣẹ́ àwùjọ mìíràn bí MD DHMH àti Àjọ tó ń ṣe Àtúngbéyẹ̀wò Owó Ìtọ́jú Ìlera (HSCRC) bá ṣe pinnu.
i. Aláìsàn ti jáde láyé lái sí dúkìá
j. Àwọn aláìsàn tí a pinnu pé wọ́n bá àwọn àmúyẹ ìpegedé tí wọ́n ṣèdásílẹ̀ lábẹ́ Ètò Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera Ìpínlẹ̀ Nìkan tẹ̀lẹ̀
k. Àwọn tí wọn kò kí n ṣe ọmọ orílẹ̀-èdè Amẹ́ríkà tí wọ́n kà kún àwọn tí wọn kò tẹ̀lẹ́ àṣẹ
l. Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera àwọn tí wọn kò Pegedé fún àwọn aláìsàn tí wọ́n pegedé fún Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera
m. Àwọn aláìsàn tí a kò mọ̀ nípa wọn (àwọn akoto Doe tí ipá ti pin láti wá àti/tàbí láti Tókasí)
n. Gbèsè jíjẹ, nípasẹ̀ òfin, bí àwọn ilé-ẹjọ́ ìjọba àpapọ̀ ṣe ti pan ní dandan
o. Ìpegedé ní àwọn ètò ìwòsàn UMMS kan (tó fi mọ́: Ètò Ìjáde St. Clare, Ètò Ìbí UMMS, Ètò Ìpàkẹ́ UMSJMC).

Àwọn aláìsàn tí wọn kò ní ìdíyelófò tí a rí ní Ẹ̀ka Pàjáwìrì lábẹ́ Ẹjọ́ Pàjáwìrì ni a kò ní wòṣe fún ìrànwọ́ owó àfojúsùn títí di ìgbà tí wọn yó fi ṣètò Maryland Medicaid Psych.

**Ìpegedé fún Ìrànwọ́ Ìpènijà Owó**

Ìrànwọ́ ìpènijà owó wà fún àwọn aláìsàn tí wọn kò pegedé fún ìrànwọ́ owó lábẹ́ ìtọ́nisọ́nà àkọ́kọ́ àgbékalẹ̀ yìí, ṣùgbọ́n ẹni tí gbèsè owó ìtọ́jú rẹ̀ fún oṣù méjìlá (12) bá kọjá ìdá 25% owó tó ń wọlé fún ẹbí náà lọ́dọọdún.

- Iye owó ìtọ́jú tí kò ní ìdíyelófò tó jẹ ní àwọn ibùdó ìlera tó ń ṣiṣẹ́ pẹ̀lú UMMS la yó wò láti pinnu ìpegedé aláìsàn (tó fi mọ́ akoto tó ti wọ gbèsè, àyàfi àwọn akoto tí wọ́n ti lọ ilé-ẹjọ́ tí wọ́n sì ti gba ìdájọ́) àti èyíkéyìí owó ìtọ́jú tí a rò.
- Fún àwọn aláìsàn tí wọ́n pegedé fún ìtọ́jú ẹ̀dínwó lábẹ́ àwọn àmúyẹ ìrànwọ́ owó tí wọ́n tún bá àwọn àmúyẹ ìrànwọ́ ìpènijà owó, UMMS yó fọwọ́sí àpapọ̀ ẹ̀dínwó tó yẹ.
- Láti ṣe ìṣirò owó tó ń wọlé fún ẹbí, UMMS yó ṣàmúlò àwọn àmúyẹ kannáà tó wà ní abala Ìpegedé fún Ìrànwọ́ Owó àgbékalẹ̀ yìí láti ṣe ìṣirò àwọn ohun ìní, iye owó tó ń wọlé fún ẹbí, àti ìwọn ẹbí.

- Ní kété tí a bá fọwọ́sí ìrànwọ́ ìpènijà owó fún aláìsàn, ètò yó bẹ̀rẹ̀ fún oṣù ọjọ́ ìpegedé àkọ́kọ́ fún ìtọ́jú àti ọdún kan ṣaájú ìpinnu náà. UMMS lè pinnu láti sún àkókò ìpegedé fún ìpènijà owó sẹ́yìn tàbí síwájú bó ṣe le wò kó rí.
- Ìrànwọ́ ìpènijà owó yó wà fún aláìsàn àti àwọn mọ̀lẹ́bí tó bá pegedé tí wọ́n gbé ilé náà fún iye ẹ̀dínwó tí a fọwọ́sí àti àkókò ìpegedé fún ìtọ́jú tó yẹ tí yó sì tẹ̀síwájú láti pegedé fún ìtọ́jú ẹ̀dínwó nígbà tó bá ń bẹ̀rẹ̀ fún ìtọ́jú ní ibùdó ìlera kannáà láàrin gbèdéke oṣù 12 náà bẹ̀rẹ̀ láti ọjọ́ tí wọ́n gba ìtọ́jú ẹ̀dínwó náà. Láti yàgò fún ẹ̀dà ìpinnu ìpegedé UMMS fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ àti ẹ̀dínwó, aláìsàn náà tàbí àwọn mọ̀lẹ́bí tó pegedé yó fi ìpegedé aláìsàn náà tàbí mọ̀lẹ́bí fún ìtọ́jú ẹ̀dínwó náà tó UMMS létí.

Gbogbo ìpegedé, àìpegedé, àti àwọn ìlànà fún àwọn àmúyẹ ìrànwọ́ owó àkọ́kọ́ mìíràn wà fún àwọn àmúyẹ ìrànwọ́ ìpènijà owó, àyàfi tí a bá sọ ohun tó yàtọ̀ sí bí a ṣe sọ lókè.

**IV. Bíbẹ Ẹ̀bẹ̀ Kòtẹ́milọ́rùn lórí Ìpinnu Ìpegedé fún Ìrànwọ́ Owó**
Àwọn aláìsàn tí a kọ ìforúkọsílẹ̀ ìbèrè fún ìrànwọ́ owó wọn lè bẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn lórí ìpinnu náà. Ẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn lè jẹ́ sísọ lẹ́nu tàbí kíkọ. A gba àwọn aláìsàn níyànjú láti fi àlékún àkọsílẹ̀ ṣọwọ́ tó ń sọ ìdí tí kò ṣe yẹ kí ìbéèrè wọn jẹ́ kíkọ.

Tí aláìsàn kan bá fẹ́ láti bẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn, UMMS yó:

- Fi tó aláìsàn náà létí pé Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìlera àti Ìpèpè wà láti ṣe ìrànwọ́ fún wọn tàbí aṣojú tí wọ́n fún láṣẹ láti forúkọsílẹ̀ fún ẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn.
- Pèsè àdírẹ̀sì, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀, ímeèlì, àdírẹ̀sì ìwé ìfiránṣẹ́, àti ojú-òpó wẹ́ẹ̀bù Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìlera àti Ìpèpè: Ilé-iṣẹ́ Agbẹjọ́rò Àgbà, Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìlera àti Ìpèpè | 200 St. Paul Place, 16th Floor, Baltimore, MD 21202 | Phone: (410) 528-1840 | Toll-free in Maryland 1-877-261-8807 | Fax: (410) 576-6571 Ímeèlì: heau@oag.state.md.us
- Ṣe àkọsílẹ̀ àwọn ẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn láàrin aláìsàn tí a gbà láti ìta àti ohun èlò ìṣiṣẹ́ fún àtúnyẹwò nípasẹ̀ ìpele àwọn alákóso tó ga ju aṣojú tó tako ìbéèrè àkọ́kọ́.
- Fi lẹ́tà ìpinnu ìkẹhìn ṣọwọ́ sí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn aláìsàn tí wọ́n ti kọ ìwé ẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn ránṣẹ́.

**<u>Èrí Ìpegedé àti Àwọ̀ṣe tó tara Olùpèsè Wáyé</u>**
Níbi tí ànfàání ẹ̀kọ́, ìlera, àti/tàbí ọmọnìyàn bá wà, àwọn ọmọ ikọ̀ ilé ìwòsàn UMMS lè bèrè fún ẹ̀rí ìpegedé fún ìrànwọ́ owó ti àwọn aláìsàn tí wọ́n kò ríbi san tàbí tó ṣeéṣe kí wọ́n má sanwó ìtọ́jú ara wọn. Àwọn ọmọ ikọ̀ ìwòsàn gbọdọ̀ fi ìdí tó bá fẹsẹ̀rinlẹ̀ tí aláìsàn fi gba ìtọ́jú sílẹ̀. Ilé-iṣẹ́ UMMS tó ń Alámójútó Owó Ìtọ́jú àwọn Aláìsàn yó ṣe àgbéyẹ̀wò ìpegedé aláìsàn fún Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera àti ìrànwọ́ Owó. Ìgbìmọ̀ tó ń rísọ́rọ̀ Ẹ̀rí Ìpegedé fún Ìrànwọ́ Owó ní ìpele àjọ alábàṣepọ̀, tó ní àwọn adarí ìwòsàn àti owó nínú, yó bèrè fún àlàyé tí ilé-iṣẹ́ tó ń rísọ́rọ̀ owó ìtọ́jú fi sílẹ̀ tí yó sì pinnu ìkẹhìn bóyá kó fọwọ́sí ẹ̀rí ìpegedé fún ìrànwọ́ owó.

Tí wọ́n bá ti gba ẹ̀rí ìpegedé ìrànwọ́ owó, ó ṣì yẹ kí àwọn aláìsàn parí ìgbésẹ̀ ìforúkọsílẹ̀ fún ìrànwọ́ owó, tó sì le kojú àyẹ̀wò ìpegedé àfojúsùn, bó ti ṣe wà nínú àgbékalẹ̀ yìí.

**V. Ìfitónilétí pé Ìrànwọ́ Owó wà**
UMMS yó gba àwọn aláìsàn, àwọn ẹbí aláìsàn, àti àwọn aṣojú tí wọ́n fún ní àṣẹ nímọ̀ràn nípa wíwà ìrànwọ́ owó nípasẹ̀ àwọn ìfitónilétí àlẹ̀mọ́de àti Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó. Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó fi ń tó aláìsàn létí nípa ìrànwọ́ owó tó wà nílẹ̀ àti àwọn ètò owó sísan, tó fi mọ́ àpèjúwe

Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó UMMS, ó ń ṣàlàyé bí ènìyàn ṣe lè forúkọsílẹ̀ bèrè ìrànwọ́ owó, tó tún pẹ̀lú àpèjúwe àwọn ẹ̀tọ́ àti ojúṣe aláìsàn nípa owó ìtọ́jú ilé ìwòsàn àti bí wọ́n ṣe lè gbàá lábẹ́ òfin.

- UMMS yó gbé àwọn ìfitónilétí ìrànwọ́ owó sí ọ̀kọ̀ọ̀kan àwọn iyàrá pàjáwìrì ilé ìwòsàn UMMS (tó bá wà), àwọn iyàrá ìtọ́jú, àwọn àyè tí àwọn aláìsàn ma ń wà àti ilé-iṣẹ́ tó ń rísọ́rọ̀ owó ìtọ́jú aláìsàn. A yó tún fi ìfitónilétí pé ìrànwọ́ owó wà ránṣẹ́ sí aláìsàn náà pẹ̀lú àwọn àkọsílẹ̀ aláìsàn.
- A yó pèsè Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó kí a tó gba aláìsàn àti kí a tó dá aláìsàn sílẹ̀ kó máa lọ ilé ní gbogbo ìgbà tí wọ́n bá ní ohun ṣe ní ilé ìwòsàn, pẹ̀lú àkọsílẹ̀ ilé ìwòsàn kọ̀ọ̀kan, yó sì wà ní àrọ́wọ́tó gbogbo àwọn aláìsàn lọ́fẹ̀ẹ́ tí wọ́n bá bèrè fún-un, nípasẹ̀ ímeèlì àti nínú iyàrá pàjáwìrì (tó bá wà) àti àwọn iyàrá ìtọ́jú.
- Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó àti Ìforúkọsílẹ̀ fún Ìrànwọ́ Owó yó tún wà lọ́fẹ̀ẹ́ fún gbogbo àwọn aláìsàn tó bá fẹ́, nípasẹ̀ ímeèlì àti ní iyàrá pàjáwìrì (tó bá wà) àti àwọn iyàrá ìtọ́jú.
- Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó, Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó, àti Ìforúkọsílẹ̀ fún Ìrànwọ́ Owó ni a yó tún gbé sí ojú-òpó wẹ́ẹ̀bù UMMS (www.umms.org).

**<u>Àkóónú Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó</u>**

Ní àfikún àkóónú tí a tọ́ka sí ní òkè, Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó yó ní:

- Ojú-òpó wẹ́ẹ̀bù àti (àwọn) àyè tó f'ojú hàn níbití àwọn aláìsàn lè ti gba fọ́ọ̀mù àgbékalẹ̀ ìrànwọ́ owó àti ti ìforúkọsílẹ̀ fún ìrànwọ́ owó.
- Ìtọ́nisọ́nà lórí bí ènìyàn lè gba ẹ̀dà ọ̀fẹ́ fọ́ọ̀mù àgbékalẹ̀ ìrànwọ́ owó àti ti ìforúkọsílẹ̀ fún ìrànwọ́ owó gbati méèlì.
- Àkọsílẹ̀ pé ìtumọ̀ àwon ìwé ìrànwọ́ owó wà.
- Ẹ̀ka tó ń rísọ́rọ̀ àwọn Oníbààrà, Ẹ̀ka Ilé Ìwòsàn UMMS tó ń rísọ́rọ̀ bí àwọn Oníbààrà ṣe ń Sanwó, tó wà láti ṣe ìrànwọ́ fún aláìsàn, àwọn ẹbí aláìsàn, tàbí aṣojú tí aláìsàn fún ní àṣẹ ní àgbọ́yé àkọsílẹ̀ wọn, ní àgbọ́yé ẹ̀tọ́ àti ojúṣe aláìsàn nípa àkọsílẹ̀ náà, kẹ́kọ̀ọ́ nípa bí wọ́n ṣe lè bèrè fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó, tàbí kẹ́kọ̀ọ́ nípa bí wọ́n ṣe lè forúkọsílẹ̀ bèrè fún Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera Maryland, tàbí èyíkéyìí àwọn ètò mìíràn tó lè báwọn san owó ìtọ́jú wọn.
- Àwọn àlàyé ìbánisọ̀rọ̀ fún Ètò Ìrànwọ́ Ìtọ́jú Ìlera Maryland
- Ìfitónilétí pé àwọn owó dókítà kò sí nínú ìwé àkọsílẹ̀ ilé ìwòsàn tí a yó sì gbàá lọ́tọ̀.
- Ìfitónilétí tó sọ fún àwọn aláìsàn pé wọ́n ní ẹ̀tọ́ láti bèrè fún iṣirò àpapọ̀ owó tí ilé ìwòsàn ń gbà fún àwọn ìtọ́jú tí kìí ṣe pàjáwìrì àti àwọn ìlànà tó yẹ kí ilé ìwòsàn pèsè fún àwọn iṣẹ́ akọ́ṣẹ́mọṣẹ́.
- Ìfitónilétí pé àwọn aláìsàn tí wọ́n bá pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó lè má san ju AGB lọ fún pàjáwìrì tàbí ìtọ́jú mìíràn tó yẹ.
- Abala tó fi ń tó aláìsàn létí nípa ìkápá wọn láti kọ ìwé ẹ̀sùn sí HSCRC àti Ilé-iṣẹ́ Agbẹjọ́rò Àgbà Maryland.
- Abala kan fún aláìsàn láti kọ̀kọ̀ fi hàn pé wọ́n ti fi Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó UMMS tó wọn létí

A yó kọ Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó ní èdè tó yé, bí àwọn Ìbéèrè fún 501(c)(3) Òfin àwọn Ilé Ìwòsàn tó wà Lábẹ́ Ìtọ́jú tí kò Gunpá – Abala 501(r), tí yó sì wà ní èdè tí aláìsàn bá fẹ́. Bákannáà ni yó ní abala tó f'àyè gba àwọn aláìsàn láti fi hàn pé wọ́n ti fi àgbékalẹ̀ ìrànwọ́ owó tó wọn létí.

**VI. Àwọn Ìgbésẹ̀ Gbígbà Àrà Ọ̀tọ̀**

Àwọn owó tó ṣẹ́kù ní tí wọn kò tíì san lè wọ Gbèsè Àjẹsílẹ̀ tó Burú (tí a rí bí ìtọ́jú tí wọn kò sanwó rẹ̀) tí a yó sì fi rán àjọ tó ń gba owó ní ita tàbí agbẹ́jọ́rò UMMS fún ìgbésẹ̀ òfin àti/tàbí iṣẹ́ gbígbà. Àwọn àjọ ní ita àti/tàbí àwọn agbẹjọ́rò ma ń dìjọ wà fún ìṣàmúṣẹ àwọn ìbéèrè sínsin gbèsè tó wà nínú àgbékalẹ̀ yìí, àti nínú Àgbékalẹ̀ UMMS lórí Owó tó ń Wọlé àti Gbígbà Rẹ̀. Àwọn ìgbésẹ̀ owó gbígbà tí àjọ tó wà fún owó gbígbà tàbí agbẹjọ́rò UMMS gbà lórúkọ UMMS lè pẹ̀lú Àwọn Ìgbésẹ̀ Owó Gbígbà Àrà Ọ̀tọ̀ (ECAs) wọ̀nyí:

- <u>Fífi àlàyé òdì nípa ènìyàn sun àwọn àjọ tó ń rísọ́rọ̀ ìfisùn owó oníbààrà.</u> UMMS kò ní fi àlàyé òdì nípa aláìsàn tí kò ní ìdíyelófò lórí tàbí pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó sun àjọ tó ń rísọ́rọ̀ ìfisùn oníbààrà lásìkò ìtọ́jú. UMMS kò ní fi ẹ̀jọ́ sun àjọ tó ń rísọ́rọ̀ ìfisùn oníbààrà títí di ọjọ́ 180 lẹ́yìn tí wọ́n pèsè ìwé àkọsílẹ̀ owó àkọ́kọ́. Ṣaájú kí ènìyàn tó fi sun àjọ tó ń rísọ́rọ̀ ìfisùn oníbààrà, UMMS yó pinnu bóyá aláìsàn náà pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó. UMMS kò ní fi àlàyé òdì nípa aláìsàn sun àjọ tó ń rísọ́rọ̀ ìfisùn oníbààrà tí aláìsàn náà tàbí ẹni tó ní ìdíyelófò lórí bá fi tó UMMS létí ní ìbámu pẹ̀lú òfin ìjọba àpapọ̀ pé ìpinnu ẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn tàbí àtúnyẹwò ìdíyelófò ìlera ń lọ lọ́wọ́ láàrin ọjọ́ 60 tó ṣaájú, tàbí tí UMMS bá ti parí àtúnwọ̀ṣe ìkọ̀jálẹ̀ ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó tí aláìsàn náà bèrè fún tó bá parí rẹ̀ bó ṣe yẹ láàrin ọjọ́ 60 tó ṣaájú.
- <u>Bíbẹ̀rẹ̀ ẹjọ́ tako ẹni náà</u>. UMMS kò ní dá ọkọ tàbí ìyàwó tàbí ẹlòmíràn lẹ́bi fún gbèsè owó ìtọ́jú tí ènìyàn tí ọjọ́-orí rẹ̀ bá ti tó ọdún 18 jẹ. UMMS kò ní pe ẹjọ́ láti gba gbèsè àjẹsílẹ̀ títí di ó kéré jù ọjọ́ 180 tí wọ́n pèsè owó àkọ́kọ́. Ṣaájú kí a tó pe ẹjọ́, UMMS yó pinnu bóyá aláìsàn pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó. UMMS kò ní pe ẹjọ́ láti gba gbèsè àjẹsílẹ̀ tí aláìsàn náà tàbí ẹni tó ní ìdíyelófò lórí bá fi tó UMMS létí ní ìbámu pẹ̀lú òfin ìjọba àpapọ̀ pé ìpinnu ẹ̀bẹ̀ kòtẹ́milọ́rùn tàbí àtúnyẹwò ìdíyelófò ìlera ń lọ lọ́wọ́ láàrin ọjọ́ 60 tó ṣaájú. UMMS kò ní pe ẹjọ́ láti gba gbèsè àjẹsílẹ̀ tí UMMS bá ti parí àtúnwọ̀ṣe ìkọ̀jálẹ̀ ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó tí aláìsàn náà bèrè fún tó bá parí rẹ̀ bó ṣe yẹ láàrin ọjọ́ 60 tó ṣaájú.
- <u>Gbígbé ẹsẹ̀ lé akoto owó ènìyàn tàbí ohun ìní mìíràn</u>.
- <u>Yíyọ gbèsè nínú owó iṣẹ́ ènìyàn</u>. UMMS kò ní bèrè fún yíyọ gbèsè nínú owó iṣẹ́ tàbí pe ẹjọ́ tí yó pa owó iṣẹ́ aláìsàn lára tí aláìsàn náà bá pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí ẹ̀dínwó.

A lè gbé ìgbésẹ̀ ECAs lórí àwọn akoto tí wọn kò tíì jiyàn lé lórí tàbí tí kò sí lórí ètò owó sísan kankan. ECAs yó wáyé kó tó pé ọjọ́ 180 tí wọ́n kọ iye owó ìtọ́jú fún aláìsàn lẹ́yìn tí wọ́n dá aláìsàn sílẹ̀ tí ìfitónilétí yó sì ṣaájú ní ọjọ́ 45 sí ECA yó bẹ̀rẹ̀. Ìforúkọsílẹ̀ fún ìrànwọ́ owó (àti àwọn ìtọ́nisọ́nà láti parí ìforúkọsílẹ̀ náà) àti ìfitónilétí wíwà ètò owó láti fi san gbèsè ìtọ́jú, àti Ìwé Àlàyé Owó Ìtọ́jú Aláìsàn àti Ìrànwọ́ Owó yó wà papọ̀ pẹ̀lú ìfitónilétí tí a kọ yìí. Ìfitónilétí tí a kọ náà yó pẹ̀lú àwọn àlàyé wọ̀nyí:

- Àlàyé lórí bí a ṣe lè kàn síni àti ti ìlànà ní pàtó.
  - Orúkọ àti nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ fún UMMS,
  - Orúkọ àti nọ́mbà ìbánisọ̀rọ̀ fún ẹni tí yó sin gbèsè (tó bá yẹ)
  - Àlàyé bí a ṣe lè kàn síni ti Ẹ̀ka Ìrànwọ́ Owó UMMS (tàbí àjọ mìíràn tó ń ṣiṣẹ́ lórúkọ UMMS), tí a fún ní àṣẹ láti ṣàtúnṣe àwọn ìlànà ètò owó sísan (tó bá yẹ)
  - Nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ àti àdírẹ́sì ojú-òpó ayélujára ti Ẹ̀ka Ẹ̀kọ́ Ìlera àti Ìpèpè ní ilé-iṣẹ́ Agbẹjọ́rò Àgbà, tó wà láti ṣe àtìlẹ́yìn fún àwọn aláìsàn tí wọ́n kojú gbèsè ìtọ́jú ìlera.
- Iye owó tó nílò láti san gbogbo gbèsè (tó fi mọ́ èyíkéyìí owó àjẹsílẹ̀ àtẹ̀yìnwá, ìjìyà, tàbí owósan, tó bá yẹ)
- Ìtọ́ka àwọn ECA tí UMMS (tàbí àjọ tó ń gba owó lórúkọ rẹ̀, agbẹjọ́rò, tàbí ẹlòmíràn tí a fún ní àṣẹ) gbèrò láti lò lójúnà àti gba owó ìtọ́jú, kó sì sọ gbèdéke lẹ́yìn tí irúfẹ́ àwọn ECA bẹ́ẹ̀ yó bẹ̀rẹ̀.
- Gbèdéke lẹ́yìn tí irúfẹ́ (àwọn)ECA bẹ́ẹ̀ lè bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ 45 lẹ́yìn ọjọ́ tí a pèsè ìfitónilétí tí a kọ.

- Àtẹ̀jáde tó ń dábàá pé aláìsàn náà bèrè fún ètò ìgbaninímọ̀ràn lórí gbèsè,
- Àlàyé lórí Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó UMMS, àti ìfitónilétí pé ìrànwọ́ owó wà fún àwọn ènìyàn tó bá pegedé
- Àti èyíkéyìí àlàyé bí HSCRC ṣe fi lélẹ̀

A yó fi ìfitónilétí tí a kọ àti àwọn àkọsílẹ̀ ránṣẹ́ sí aláìsàn gbati méèlì, ní èdè tí aláìsàn bá fẹ́, tàbí èdè mìíràn, tí wọ́n bá ṣe sọ. Ìfitónilétí tí a kọ náà yó wà ní èdè tí a mú rọrùn ó kéré jù oní irú pọinti 10.

Ní àfikún ìwé owó tí a kọ, UMMS (àti/tàbí àjọ tó ń gba owó lórúkọ rẹ̀ tàbí agbẹjọ́rò rẹ̀) yó tiraka láti jẹ́ kí aláìsàn mọ̀ pé ìrànwọ́ owó wà tí yó sì sọ fún aláìsàn náà bó ṣe lè gba ìrànwọ́ pẹ̀lú ìgbésẹ̀ ìforúkọsílẹ̀ náà. Àgbéyẹ̀wò ìpegedé àfojúsùn yó wáyé ṣaájú ìgbésẹ̀ ECA kankan. Ní ìparí, ECA kankan kò ní bẹ̀rẹ̀ àfi tí a bá gba àṣẹ lọ́wọ́ àwọn adarí Ètò Ìpawówọlé UMMS.

Tí a bá pinnu pé aláìsàn pegedé fún ìrànwọ́ owó UMMS (àti/tàbí àjọ tó ń gba owó lórúkọ rẹ̀ tàbí agbẹjọ́rò) yó gbé gbogbo ìgbésẹ̀ tó yẹ láti jámi kúrò lórí gbogbo ECAs tí wọ́n gbé tako aláìsàn náà láti gba owó ìtọ́jú tí wọ́n fún-un lásìkò gbèdéke ìpegedé fún ìrànwọ́ owó. Irúfẹ́ àwọn ìgbésẹ̀ ọ̀hún yó pẹ̀lú àwọn ìgbésẹ̀ láti jámi kúrò lórí èyíkéyìí ìdájọ́ tako aláìsàn náà, gbẹ́sẹ̀ kúrò lórí dúkìá aláìsàn, àti yíyọ èyíkéyìí àlàyé òdì tí wọ́n fi sun àjọ tó ń rísọ́rọ̀ ìfisùn oníbàárà kúrò lórí ìwé owó aláìsàn. Gbogbo ECA yó dúró ní kété tí wọ́n bá fọwọ́sí aláìsàn fún ìrànwọ́ owó tí gbogbo owó tó kù tí aláìsàn jẹ sílẹ̀ sì jẹ́ sísan.

UMMS kò ní kópa nínú àwọn ECA wọ̀nyí:

- Títa gbèsè fún ẹlòmíràn.
- Gba owó èlé lórí àwọn owó tí àwọn aláìsàn jẹ kí á tó gba ìdájọ́ ilé-ẹjọ́.
- Bèrè fún gbígbé ẹsẹ̀ lé ilé tí aláìsàn ń gbé. Ní àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ mìíràn, ètò ìdájọ́ Ìbílẹ̀, Ìpínlẹ̀, tàbí Àpapọ̀ lè paá ní dandan pé kí wọ́n gbẹ́sẹ̀ lé dúkìá, ṣùgbọ́n UMMS kò ní mú títà tàbí títi ilégbé aláìsàn ní ipá.
- Bèrè tàbí gbé ìgbésẹ̀ tó fa kí ilé-ẹjọ́ pàṣẹ kí àwọn agbófinró mú aláìsàn.
- Gbẹ́sẹ̀ lé dúkìá aláìsàn tó dolóògbé tí UMMS bá mọ̀ pé aláìsàn tó dolóògbé ọ̀hún pegedé fún ìtọ́jú ọ̀fẹ́ tàbí tí iye tí dúkìá náà tó lẹ́yìn tí wọ́n yọ owó orí kéré sí ìdajì gbèsè tó jẹ. Wàyí ò, UMMS lè fún ẹbí aláìsàn tó dolóògbé ní ànfààní láti forúkọsílẹ̀ bèrè fún ìrànwọ́ owó.
- Bèrè fún sísan gbèsè àjẹsílẹ̀ ṣaájú kí a tó pèsè ìtọ́jú tó yẹ.

| UNIVERSITY of MARYLAND MEDICAL SYSTEM<br>Ètò Owó tó ń Wọlé | OJÚ-ÌWÉ:<br>12 NÍNÚ 13 | NỌ́MBÀ ÀGBÉKALẸ̀:<br>RCS - 01 |
|---|---|---|
| | DÉÈTÌ TÓ BẸ̀RẸ̀:<br>09/18/19 | (ÀWỌN) DÉÈTÌ ÀTÚNYẸWÒ:<br>07/01/23 |
| ÀKÒRÍ: UMMS Àgbékalẹ̀ Ìrànwọ́ Owó | | |

## ÀWỌN ÀSOMỌ́:

## ÀSOMỌ́ A: Ìwọ̀n Owó Sísan – Ìtọ́jú Ẹ̀dínwó

| Ojúlé Ìwọ̀n (HH) | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | Wo Ìwọ̀n Ìtọrẹ-àánú UMMS ní abẹ́ |
|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $14,580 | $19,720 | $24,860 | $30,000 | $35,140 | $40,280 | |

| 2022 Maryland Dept of Health (MDH) Awọn Itọsọna Idiwọn Yiyẹ ni Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Ojúlé Ìwọ̀n (HH) | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | Wo Ìwọ̀n Ìtọrẹ-àánú UMMS ní abẹ́ |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $20,120 | $27,225 | $34,312 | $41,400 | $48,504 | $55,592 | |

| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé ti Ìtọrẹ-àánú Ìrànwọ́ Owó UMMS | | | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|---|---|
| Tí àpapọ̀ ìpele owó tó ń wọlé fún ilé rẹ (HH) bá wà ní tàbí wà lábẹ́: | | | | | | | O pegedé fún ìpele ìtọrẹ-àánú wọ̀nyí ní UMMS: |
| Ojúlé Ìwọ̀n (HH) | 1 | 2 | 3 | 4 | 5 | 6 | |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $40,240 | $54,450 | $68,624 | $82,800 | $97,008 | $111,184 | **Ìtọrẹ-àánú ìdá 100%** (Ó ṣe déédé ìdá 200% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $42,252 | $57,173 | $72,055 | $86,940 | $101,858 | $116,743 | **Ìtọrẹ-àánú ìdá 90%** (Ó ṣe déédé ìdá 210% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $44,264 | $59,895 | $75,486 | $91,080 | $106,709 | $122,302 | Ìtọrẹ-àánú ìdá 80% (Ó ṣe déédé ìdá 220% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $46,276 | $62,618 | $78,918 | $95,220 | $111,559 | $127,862 | **Ìtọrẹ-àánú ìdá 70%** (Ó ṣe déédé ìdá 230% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $48,288 | $65,340 | $82,349 | $99,360 | $116,410 | $133,421 | Ìtọrẹ-àánú ìdá 60% (Ó ṣe déédé ìdá 240% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $50,300 | $68,063 | $85,780 | $103,500 | $121,260 | $138,980 | **Ìtọrẹ-àánú ìdá 50%** (Ó ṣe déédé ìdá 250% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $52,312 | $70,785 | $89,211 | $107,640 | $126,110 | $144,539 | **Ìtọrẹ-àánú ìdá 40%** (Ó ṣe déédé ìdá 260% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $54,324 | $73,508 | $92,642 | $111,780 | $130,961 | $150,098 | **Ìtọrẹ-àánú ìdá 30%** (Ó ṣe déédé ìdá 270% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $56,336 | $76,230 | $96,074 | $115,920 | $135,811 | $155,658 | **Ìtọrẹ-àánú 20%** (Ó ṣe déédé ìdá 280% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |
| Ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé (dé Ọ̀pin) | $58,348 | $78,953 | $99,505 | $120,060 | $140,662 | $161,217 | **Ìtọrẹ-àánú 10%** (Ó ṣe déédé ìdá 290% ìwọ̀n Owó tó ń Wọlé Lọ́dọọdún ti MDH) |

*Gbogbo Ẹ̀dínwó tí a sọ sí òkè ni yó wà fún iye owó tó yẹ kí aláìsàn san fúnra rẹ̀ lẹ́yìn tí wọ́n san ìdíyelófò padà.
*Iye owó tí wọ́n kọ fún àwọn aláìsàn tí wọ́n pegedé fún Ìtọ́jú Ẹ̀dínwó lórí ìwọ̀n owó sísan (tàbí fún Ìrànwọ́ Ìpènijà Owó) yó kéré sí iye owó tí wọ́n ma ń kọ fún àwọn tí wọ́n ní ìdíyelófò (AGB) lórí, èyí tó jẹ́ pé ní Maryland ó jẹ́ owó tí Àjọ tó ń rísọ̀rọ̀ Àtúnyẹ̀wò Owó Ìtọ́jú Ìlera (HSCRC) ṣèdásílẹ̀. UMMS ma ń pinnu AGB nípasẹ̀ lílo iye owó tí Medicare yó f'àyè gbà (tó fi mọ́ iye owó tí ẹni tó jẹ àǹfààní ẹ̀ yó san fúnra ẹ̀, èyí tó jẹ́ iye owó HSCRC; èyí la mọ̀ sí "ìlànà Medicare tó ṣeéṣe".

**Bẹ̀rẹ̀ láti 7/1/23**

**ÀWỌN ÀGBÉKALẸ̀ TÓ NÍ ÌBÁTAN:**
Àgbékalẹ̀ àwọn Gbígbà àti Sísan UMMS
Àgbékalẹ̀ Ètò Ìsanwó UMMS

**ẸNI TÓ NI ÀGBÉKALẸ̀:**
Ètò Ìpawówọlé UMMS

**TI FỌWỌ́SÍ:**
Àgbékalẹ̀ Àkọ́kọ́ tí Ìgbìmọ̀ tó ń rísí Ìtẹ̀lé Àṣẹ Fọwọ́sí: 09/18/19
Àwọn Àtúngbéyẹ̀wò tí Ìgbìmọ̀ tó ń rísí Ìtẹ̀lé Àṣẹ Fọwọ́sí: 10/19/2020, 11/07/22

Ìpele Ìṣẹ̀ òhun Òṣì Àpapọ̀ ati Maryland Department of Health Opin Iyẹyẹ Owo ti Ọdọọdun ti imudojuiwọn: 07/01/20, 07/01/21, 07/01/22, 07/01/23

Ìgbìmọ̀ tó ń rísí Ìtẹ̀lé Àṣẹ (ECC) ní UMMS ló fọwọ́sí àgbékalẹ̀ yìí ní 19 oṣù Kẹ̀wá, ọdún 2020. A fọwọ́sí àgbékalẹ̀ yìí fún:

- Ibùdó Ìlera UM St. Joseph (UMSJMC) bẹ̀rẹ̀ 1 oṣù kẹfà, ọdún 2013
- UM Midtown Campus (MTC) bẹ̀rẹ̀ láti 22 oṣù kẹ̀sán, ọdún 2014
- Ibùdó Ètò Ìlera UM Baltimore Washington (UMBWMC) bẹ̀rẹ̀ láti 1 oṣù keje, ọdún 2016.
- UM Shore Regional Health (UMSRH) bẹ̀rẹ̀ láti 1 oṣù kẹ̀sán, ọdún 2017.
- Ibùdó Ìlera UM Charles (UMCRMC) bẹ̀rẹ̀ láti 2 oṣù kejìlá, ọdún 2018.
- Ibùdó Ìlera UM Upper Chesapeake Health (UCHS) bẹ̀rẹ̀ láti 1 oṣù keje, ọdún 2019
- Ibùdó Ìlera UM Capital Region Health (UMCRH) bẹ̀rẹ̀ láti 18 oṣù kẹ̀sán, ọdún 2019